## ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**ADÚRÀ OGUN (APÁ KINÍ)**

**OSÙ KEJE, ỌDÚN 2021**

Ìwé Mímọ́ kíkà: Orin Dáfídì 2

Ìjẹ́wọ́: Lúkù 18:1

**ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA**

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ìránṣẹ́ òkùnkùn tóti gbàbọ̀dè lòdì sími, kí àṣírí rẹ tú, ko sì gba ìtìjú, ní orúkọ Jésù.
6. Ọlọ́run, dìde, máṣe jẹ́ kí pàkúté àwọn ìkà múmi , ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa dìde, jẹ́ kí ìrúnú agbára Ọlọ́run jó gbogbo irúgbìn òkùnkùn nínú ayé mi run, ní orúkọ Jésù.
8. Àwọn ẹ̀mí òkùnkùn jògojògo, tọ́ n dúró láti jẹ ògo mi, ẹ jẹ ara yín, kẹ sì gbẹ dànù, ní orúkọ Jésù.
9. Ìwọ ilẹ̀, dámiláre, ko sì gbé gbogbo ọ̀ta àyànmọ́ mi mì, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo òpó dídìde àti ṣíṣubú padà, tó ndámilóró, fọ́ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
11. Olúwa, jẹ́ kí gbogbo òpó àwọn ọ̀tá mí fọ́ sí wẹ́wẹ́ di éérú, ní orúkọ Jésù.
12. Ọlọ́run dìde, jẹ́ kí àwọn ọ̀tá mi lọ sí ibi tí wọn kòní bọ́ nínú rẹ̀, ní orúkọ Jésù.
13. Àwọn tó rí ìtìjú mi látẹ́yìn wá, yóò rí ògo nínú mí nígbà tí wọ́n bá rími báyìí, ní orúkọ Jésù.
14. A ó gbè orí mi sókè gaju àwọn ọ̀tá mi lọ, àwọn ọ̀tá mi yóò sì sìn mí, ní orúkọ Jésù.
15. Mo gbé ìtìjú àti ẹ̀ṣín mi sin nípa agbára tówà nínú orúkọ Jésù.
16. Àwọn agbára tó fẹ́ kí n sin Ọlọ́run láìrésì, kú, ní orúkọ Jésù.
17. Ọlọ́run, dìde, jẹ́ kí àwọn ọ̀tá mi lúwẹ̀ nínú ẹ̀jẹ̀ wọn, ní orúkọ Jésù.
18. Àwọn ogun mi, gba ìparun nípa àwọn ọfà Ọlọ́run Olódùmarè, ní orúkọ Jésù.
19. Ọlọ́run dìde, kó gbogbo orí àwọn ọ̀tá mi papọ̀, k'Osì lọ̀ wọ́n sí wẹ́wẹ́, ní orúkọ Jésù.
20. Àwọn ángẹ́lì Ọlọ́run Alàáyè tó rorò, ẹ ṣàwárí àwọn ìnira mi, kẹ sì fòpin sí wọn, ní orúkọ Jésù.
21. Àyànmọ́ mi yóò dìde, yóò sì mú ijákulẹ̀ bá àwọn ọ̀tá mí, ní orúkọ Jésù.
22. Àwọn ìṣoro tí wọ́n yàn láti bá ohun rere gbogbo jẹ́ nínú ayé mi , kú, ní orúkọ Jésù.
23. Àwọn ángẹ́lì Ọlọ́run Alàáyè tó rorò, ẹ pa gbogbo àwọn ọmọ ogun omi tí wọ́n yàn lòdì sími, ní orúkọ Jésù.
24. Ìṣòrokíṣòro tí yóò tún mú ìṣòro tó ga púpọ̀ wọnú ayé mi, kú, ní orúkọ Jésù.
25. Ọlọ́run dìde, jẹ́ kí ilẹ̀ lánu, kó sì gbé idà àwọn ọ̀tá mi mì, ní orúkọ Jésù.
26. Òkun òkùnkùn tó nrú dìde lòdì sími, gbẹ́ dànù, ní orúkọ Jésù.
27. Àwọn agbára tí wọ́n yàn láti fòpin sí ayé mi, kú nípa iná, ní orúkọ Jésù.
28. Ọlọ́run dìde, jẹ́ kí agbára àwọn ọ̀tá mi pawọ́n run, ní orúkọ Jésù.

29. Ọlọ́run dìde, jẹ́ kí ògo mi gbé gbogbo ìtìjú inú ìdílé mi mì, ní orúkọ Jésù.
30. Ọlọ́run dìde, jẹ́ kí ìtìjú àti ẹ̀tẹ́ di ohun àjèjì nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
31. Ọ̀pá ìbínú Ọlọ́run, dìde lòdì sí àwọn tó nyọ àyànmọ́ mi lẹ́nu, ní orúkọ Jésù.
32. Ibi gbogbo tí àyànmọ́ mi ti ṣubú, di gbígbé sókè padà báyìí, ní orúkọ Jésù.
33. Ọlọ́run dìde, mú ìjì ìpayà kúrò nínú àyànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
34. Àwọn Ọwọ́ Ọlọ́run, dìde nínú ìbínú, ti àwọn ọ̀tá mi sínú ọ̀fìn tí wọ́n wà fún mi, ní orúkọ Jésù.
35. Gbogbo ogun tí wọ́n yàn láti jẹ́ kí nma dìde, kí n tún ṣubú padà, kú, ní orúkọ Jésù.
36. Ọlọ́run dìde, rán Fáráò tó le láti bá Fáráò mi jagun, ní orúkọ Jésù.
37. Ọlọ́run dìde, ṣemílọ̀ṣọ́ níwájú àwọn tó nfojú tẹ́mbẹ́lú mi, ní orúkọ Jésù.
38. Gbogbo agbára tó de ògo mi mọ́ ohun atẹ̀yìnwá, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
39. Agbára ìkà yóówù, tó nlo ògo mi fún ànfàní tirẹ̀, ya wèrè, kosì kú, ní orúkọ Jésù.
40. Ẹmi iku yoowu, ni àwọn ìbùkún mi wà nínú rẹ, gba àra Ọlọ́run, kosì pọ̀ wọ́n jáde, ní orúkọ Jésù.